# ÀTÚNṢE NÍNÚ ÈTÒ SÍTÁǸPÙ OÚNJẸ TI J KÍ ÀWỌN ÀLEJÒ TÍ WỌ́N NÍ KÁÀDÌ ỌMỌ ONÍLẸ̀ PÚPỌ̀ SÍ LÈ GBA ÀWỌN ÀǸFÀÀNÍ SÍTÁǸPÙ OÚNJẸ

### N Kì í ṣe ọmọ ìlú Amẹ́ríkà? Ṣe mo lè gba sítáǹpù oúnjẹ ?

- O lè gba sítáǹpù oúnjẹ **nísisìyí** bí o bá jẹ àlejò tí ó ni káàdi ọmọọlè, àti bi ìwọ, ìyàwó tábì ọkọ rẹ, tàbí àwọn òbí rẹ bá ti ṣiṣẹ́ ni ìlú Amẹ́ríkà (Àwọn òṣìṣẹ́ ọ́fíìsì sítáǹpù oúnjẹ yòó jẹ́ ki o mọ̀ bóyá o ti ṣiṣé tó látí gba sítáǹpù oúnjẹ). Àwọn tí wọ́n sá wá sí ìlú Amẹ́ríkà fún ààbò àti àwọn ajooji tí wọ́n ṣí wá sí ìlú Amẹ́ríkà yẹ fún sítáǹpù oúnjẹ. O tún lè gba sítáǹpù oúnjẹ bí o bá ń gbé ní ìlú Amẹ́ríkà ní ọjọ́ kejìlélógún, oṣù kẹjọ, ọdún 1996 láì tàpá sí òfin ìlú Amẹ́ríkà ***àti*** (1) bí o bá jẹ́ ọmọ ọdún márùnúndínláàádọ́rin (bí a ba bí ẹ ní ọjọ́ kejìlélógún, oṣú kẹjọ, ọdún 1931, tàbí kí ọjọ́ yìí tóó pé), ***tàbí*** (2) o ń gba owó ìrànlọ́wọ́ lọ́wọ́ ìjọba fún àìlera ***tàbí*** (3) o kò tó ọmọ ọdún méjìdínlógún. O tún lè gba sítáǹpù oúnjẹ bí o bá ti wà ní ìlú Amẹ́ríkà ní ipò tí ó yẹ fún ọdún márùnún

### Ìyípadà wo ni a ti ṣe?

- Ní ọjọ́ kẹtàlá, oṣù karùnún, ọdún 2002, Aàrẹ Bush fi ọwọ́ sí ìwé ofin "Ìpèsè fún ọjọ́ iwájú fún ààbò àwọn oko ọ̀gbìn àti ìgbèríko" (Farm Security and Rural Investment Act of 2002) – tí o gba àwọn àlejò akúsẹ̀ẹ́ àti àwọn ti ìjọba gbà láàyè láti ṣí wá sí ìlú Amẹ́ríkà láti gba sítáǹpù oúnjẹ bí owó oṣù wọn bá bá owó oṣù àwọn tí ó lè gba sítáǹpù oúnjẹ mu.

### Nígbà wo ni òfin yìí máa bẹ̀rẹ̀?

- Àwọn àlejò ti ìjọba gbà láàyè láti ṣí wá sí ìlú Amẹ́ríkà, tí ofin 2002 yìí ń sọ nípa rẹ̀, lè bẹ̀rẹ̀ sí í gba àǹfààní sítáǹpù oúnjẹ láti ọjọ́ kìíní, oṣù kẹwàá, ọdún 2002, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni wọ́n máa bẹ̀rẹ̀ lẹ́hìn ọjọ́ yìí. Àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí tún ṣe àlàyé sí i, nípa ìgbà tí ènìyàn lè bẹ̀rẹ̀ sí gba sítáǹpù oúnjẹ.

Òfin 2002 gba àwọn àlejò tí ìjọba gbà láàyè láti ṣí wá sí ìlú yìí, tí wọ́n sì ti ṣe gbogbo nǹkan tí ètò sítáǹpù oúnjẹ ń bèèrè, láàyè láti yẹ fún ètò yìí, ÀTI àwọn:

- ✔ Tí wọ́n ń gba ìrànlọ́wọ́ lọ́wọ́ ìjọba fún àìlera ( bí i SSI tàbí owó òògùn fún àìlera) àwọn wọ̀nyí lè bẹ̀rẹ̀ sí i gba àǹfààní yìí láti **ọjọ kìíní, oṣù kẹwàà, ọdún 2002;**
- ✔ tí wọ́n ti ń gbé ní ìlú Amẹ́ríkà fún ọdún márùnún tí wọ́n si yẹ láti wà nínú ètó sítáǹpù oúnjẹ (àwọn wọ̀nyí lè bẹ̀rẹ̀ sí i gba àǹfààní yìí látí **ọjọ kìíní oṣù kẹrin ọdún 2003**); tàbí
- ✔ àwọn tí wọn kò tó ọmọ ọdún méjìdínlógún, tí wọ́n sì wọ ìlú Amẹ́ríkà lẹ́hìn ọjọ́ kejìlélógún, oṣù kẹjọ, ọdún 1996 (àwọn wọ̀nyí lè bẹ̀rẹ̀ sí i gba àǹfààní yìí láti **ọjọ kìíní oṣù kẹwàá, ọdún 2003**).

### Àwọn àlejò tí ìjọbà gbà láàyè láti ṣí wá sí ìlú yìí wo ni ó yẹ fún ètò yìí?

- Àwọn àlejò tí ó yẹ ni àwọn àlejò tí wọ́n ní káàdi ọmọ ilé, àwọn tí wọ́n sá wá sí ìlú yíí fún ààbò, àwọn ọ̀daràn tí wọ́n sá wá sí ìlú yíí fún ààbò, àwọn tí ìjọba gbà pé kí wọ́n gbé ìlú yìí bí o tilẹ̀ jẹ́ pé òfin ìlú ní kí wọ́n padà sí ìlú wọn, àwọn tí wọ́n wá sí ìlú yìí láti ìlú Kúbà tàbí Héítì, àwọn arúfin tí ilé-Iṣẹ́ ìsọnidọmọìlú (Immigration and Naturalization Service - INS) gbà láàyè láti gbé ní ìlú yìí fún nǹkan bí ọdún kan, àwọn tí ó wọ ìlú yìí pẹ̀lú àdéhùn pàtàkí láàárín àwọn àti ìjọba, àti àwọn tí wọ́n ní wàhálà burúkú pẹ̀lú ọkọ, aya, tàbí pẹ̀lú alábàágbé.

**Ṣé òfin tuntun yìí yí ètò padà fún àwọn ènìyàn tí ó ń gba àǹfààní yìí tẹ́lẹ̀?**

- Rárá.  Ẹnikẹ́ni tí o ti ń gba àǹfààní yìí tẹ́lẹ̀ yóò tẹ̀síwájú láti gbà á.

**Ṣé òfin yìí gbà kí àwọn ènìyàn tí kì í ṣe ọmọ ìlú yìí, ṣùgbọ́n tí ìjọba ṣàánù fún láti jẹ́ kí wọ́n gbé ìlú yìí, gba sítáǹpù oúnjẹ?**

- Bẹ́ẹ̀ ni.  Nítorí òfin 2002, àwọn tí wọ́n sá wá sí ìlú yìí fún ààbò, àwọn ọ̀daràn tí wọ́n sá wá sí ìlú yìí fún ààbò,àwọn ọmọ ìlú Amẹ́ríkà tí wọ́n wá láti Ásíà, àti àwọn tí wọ́n wá láti ìlú Kúbà àti Héítì lè gba sítáǹpù oúnjẹ jù fún ọdún méje lọ. Bẹ̀rẹ̀ láti ọjọ́ kìíní, oṣù kẹrin, ọdún 2003, àwọn ènìyàn yìí tí kìí ṣe ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà yẹ fún sítáǹpù oúnjẹ nígbàkígbà tí owó oṣù wọn tàbí ohun ìní wọn bá bá òye tí ètò yìí wí mu.

**Ṣé Ètò sítáǹpù oúnjẹ ni ó máa pinnu pé mo jẹ́ aláìlera tàbí n kò jẹ́ aláìlera?**

- Rárá.  O gbọ́dọ̀ máa gba àǹfààní tàbí ìrànlọ́wọ́ lọ́wọ́ ìjọba fún ìfọ́jú tàbí àìlera.

**Ṣé mo lè gba àǹfààní sítáǹpù oúnjẹ fún àwọn ọmọ mi tí wọ́n jẹ́ ọmọ ìlú Amẹ́ríkà, bí èmi kò tilẹ̀ yẹ láti gba àǹfààní yìí?**

- Bẹ́ẹ̀ ni.  Kì í ṣe dandan pé kí o fún wa ní ìwé-àṣẹ nípa ara rẹ nígbà tí o bá bèèrè àǹfààní sítáǹpù oúnjẹ fún àwọn ọmọ rẹ tàbí ẹnikẹ́ni tí àǹfààní yìí tọ́ sí nínú ilé rẹ.  Ṣùgbọ́n, o ṣì ní láti pèsè ìwé àṣẹ nípa owó oṣù tàbí ohun ìní rẹ kí àwọn òṣìṣẹ́ ọ́fíìsì sítáǹpù oúnjẹ lè mọ oye àǹfààní tí ó tọ́ sí àwọn ọmọ rẹ.

**Ṣé gbígba sítáǹpù oúnjẹ lè jẹ ohun ìdènà fún mi bí mo bá fẹ́ di ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà?**

- Rárá.  Gbígba sítáǹpù oúnjẹ, kò sọ ẹni tí ó ṣí wá sí ìlú Amẹ́ríkà di "Ọmọ Ìjọba" – ìyẹn ni pé, ìjọba ìlú Amẹ́ríkà kò lè lé ẹni tí ó ṣí wá sí ìlú yìí kúrò nílùú, wọn kò lè sọ pé irú ènìyàn yìí kò gbọdọ̀ wọ ìlú, wọn kò sì lè sọ pé kò lè di ọmọ-onílẹ̀ nítorí pé ó ń gba sítáǹpù oúnjẹ.

**Báwo ni mo ṣe lè bèèrè tàbí mọ síwájú si nípa àǹfààní yìí?**

- Láti gba sítáǹpù oúnjẹ, o gbọ́dọ̀ bèèrè pẹ̀lú fọ́ọ̀mù tí o lè rí gbà ní ọ́fíìsì sítáǹpù oúnjẹ ní àdúgbò rẹ.  Ọ́fíìsì yìí máa ń wà ní ibìkan náa pẹ̀lú ọ́fíìsì ètò àǹfààní ọ̀fẹ́.
- Láti ní ìmọ̀ kíkún, jọ̀wọ́ pe ọ́fíìsì sítáǹpù oúnjẹ ní àdúgbò rẹ.  Nọ́ńbà tẹlifóònù ọfíìsì yìí wà nínú ìwé tẹlifóònú lábẹ́ "ilé-iṣẹ́ ètò ìlú" tàbí "ilé-iṣẹ́ ètò àǹfààní ọ̀fẹ́" tàbí o lè pe nọ́ńbà ọ̀fẹ́ yìí **1-800-221-5689**.
- Àwọn olùrànlọ́wọ́ ẹ̀rọ tẹlifóònù wà lárọ̀ọ́wọ́tó láti ran àwọn tí wọ́n gbọ́ èdè Sípáníìṣì nìkan lọ́wọ́.

***Sítáǹpù Oúnjẹ ti Sọ Amẹ́ríkà di Alágbára.***

*Ilé-Iṣẹ́ Ohun Ọ̀gbìn ní ìlú Amẹ́ríkà (United States Department of Agriculture – USDA) jẹ́ ilé iṣẹ́ tí ó máa ń pèsè iṣẹ́ fún ẹnikẹ́ni láìsí ojú ìsájú.*